28 FEB 1966


# IROHIN IMỌLẸ

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No 1, 475, WEDNESDAY OCTOBER 6 1965 (2)


## Enia Mẹsan Jona Ku Sinu Moto

IDỌFIAN:- Idaamu nla ba gbogbo awọn enia ti nwọn wa ninu mọto akero kan Nọmba PL. 620 nigbati mọto na nsare lọ ni oju ọna ti ọkunrin kan ninu awọn ero ti nwọn wa ninu mọto na ṣa ina sinu siga ti mọto na si gbina ni Irọlẹ ana ọjọ iṣẹgun ti iṣe ọjọ karun oṣu yi.

Onirohin wa ni Ilọrin fi ye wa wipe mọto akero na kuro ni ilu kan ti nwọn npe ni Idọfian ni eti Ilọrin mọto na si nlọ si Ilọrin nigbati ijamba na fi ṣẹlẹ.

Gẹgẹbi Irohin ti awọn ọlọpa fi ye Oniwe Irohin wa agbọ wipe nigbati mọto na ti kuro ni Ilọrin Idọfian tan omura lati lọ si Ilọrin ọkan ninu awọn ero ti nwọn wa ninu mọto akero na ba yọ Iṣana ninu apo rẹ ti o si yọ siga jade,

Ṣugbọn bi o ti ṣa ina si ẹnu siga owo rẹ ko mọ wipe epo mọto wa nibiti on joko si bi o si ti ṣa ina si siga na ina ọwọ rẹ ba ranmọ epo mọto ti epo na si gbina.

Lojukanna ni gbogbo awọn ero ti nwọn wa ninu mọto na ba bẹrẹsi ki gbe pe onimọto na wipe ki o duro ṣugbọn nigbati mọto na yio fi duro o awọn enia mẹsan ti nwọn joko ti ọkunrin na ina ti jo gbogbo wọn awọn yoku si sare sọ kalẹ.

Awọn ọlọpa aṣọmọto ti gbe gbogbo awọn oku inu mọto na lọ si ile iwosan ilu Ilọrin fun ayẹwo awọn Dọkita.

Ki Oluwa ma jẹki a rin ni ọjọ ti ebi npa ọna.

# ỌKUNRIN KAN ṢA ENIA MẸRIN PA, O SI PA ARARẸ

SHAGAMU:- Ọrọ di pẹntọka ni abuleko kan ti a npe ni Orile-Oko lẹba Shagamu nigbati Ọkunrin kan ṣa awọn enia mẹrin pa bamubamu ti Ọkunrin na tun yin ibọn pa ara rẹ lẹhinti o ti pa awọn enia mẹrin na ti nwọn si ti ku patapata eyiti o fi jẹ pe lẹsẹkẹsẹ na ni Ọkunrin na tun yin ibọn pa ara rẹ ni igba kan to wa lẹba abuleko na.

Ninu irohin lati ọwọ awọn Ọlọpa ti ilu Shagamu ni nwọn ti ṣe alaye pe Ọkunrin na si lọ ka awọn enia meji kan mọle ninu awọn enia ti o fi ada ṣa na ti o si ṣa ọkan ninu awọn enia ti nwọn npe ni Pelujọla Awolesi pa ti o si ku lẹsẹkanna.

Irohin na tun fi ye wa pe bi Ọkunrin na ti fi yara Pelujola silẹ ni o tun ba Ọkunrin keji lọnu ona ti o si tun fi ada ṣa Ọgbẹni Aiyefola omo ti o ba loju ona ilẹkun rẹ eyiti o jẹ pe lẹsẹkẹsẹ na ni Ọkunrin na si ku bamubamu.

Irohin awon Ọlọpa na tun ṣe alaye pe Ọkunrin na tun bo si ẹhinkule awon enia meji ti o ti pa ti o si tun ri Obinrin kan ti iṣe eni odun marundinindota Iyaafin Fayemi Ọnafuwa ti o ndin gari lowo ti okunrin na tun ṣa a ni ada eyiti o jẹ wipe lẹsẹkẹsẹ na ni Obinrin na si ku.

Iroh'n fi ye wa pe bi okunrin na ti pa obinrin yi tan ni o ti ri ọmọ ọmọ obinrin na ti iṣe omo odun marun ti oruko re njẹ Adegbo Taiku eyiti okunrin na tun ṣa omo kunrin kekere na pa bamubamu ti o si ku ni loju kanna.

Oniwe irohin wa ni ilu Shagamu fi ye wa pe, awon Ọlọpa ti gbe oku awon enia mererin ti ọkunrin na pa pelu Okunrin na to sa awon enia na pa lo si ile iwosan ti ilu Shagamu lati ṣe ayẹwo won

Awon ebi ati ọrẹ awon enia ti Ọkunrin na sa pa ni irohin fi ye wa pe, nwon ti sọ ti ẹnu won fun awon ọlọpa lori iṣele to ṣele na.

Oniwe irohin wa to lo sibi ti iṣele na ti ṣele fi ye wa pe gbogbo awon enia to ngbe ni abuleko ti nwon npe ni Orile-Oko na ni nwon fẹ ti sa kuro ni ilu na lori ohunti o ṣẹlẹ na.

Onirohin wa tun ṣe alaye pe gbogbo ilẹkun ile awon enia na ni nwọn ti, ti patapata ati pe awon enia diẹ ti nwon nri ni opopo ilu na ni nwon ko si le sọrọ kankan ti gbogbo awon enia na fi dakẹ jẹjẹ.

Nigbati oniwe Irohin wa bere ọrọ lowo awon enia na lori iṣẹlẹ to ṣẹlẹ na, ṣugbon idahun ti awon enia na yio fi di onirohin wa lohun nipe awon ko gbọ nkankan.

Ninu irohin to tun de ọwọ wa ni a ti gbọ pe ija nla ṣẹlẹ ni ilu kan ti a npe ni Ari gidi ni iha Ariwa Ọwọ kini larin awọn ẹgbẹ oṣelu meji ti yio gbe apoti ibo silẹ ni-

WO OJU EWE KẸFA

# Alhaji Adegbenro, O Ku Orire !



ABẸOKUTA, Ninu ọṣẹ ti o kọja lọ yi ni Alhaji D. S. Adegbenro Adele Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre mu iwe iforukọsilẹ rẹ lọ fun awọn akọwe eto idibo ni Abẹokuta ti nwon si gba iwe na lowo rẹ. Aworan oke yi ni ti Alhaji Adegbenro nigbati o fun akọwe na ni iwe rẹ tan ti akọwe na si gba owo lọwọ rẹ, ti o tan nki i ku orire.

Ọpọlọpọ awọn Asoju omọ ẹgbẹ Ajumọṣe to UPGA ni a gbọ wipe awọn ko le ri awọn akọwe fun ni iwe iforukọsilẹ wọn titi ti asiko na fi kọja ṣugbọn bi ti Alhaji Adegbenro kọ. Alhaji a ti fun awọn akọwe ni iwe ti ẹ ki asiko to kọja.

Awọn oniwe Irohin Imọlẹ na ki Alhaji Adegbenro ku orire.

# FI IBO RẸ LE DẸMỌ LU-GBẸ

Ẹnyin ọmọ Yoruba, nipataki gbogbo ẹnyin ọmọ ilẹ "Ẹ karọ, ẹ o jire", to mbẹ ni Ipin lẹ Iwọ-Orun Naijiria nl mo ke si, nitoripe asiko to lati fi Ibo yin le ẹgbẹ Dẹmọnu lugbẹ gẹgẹbi owe awọn baba wa kan to sọ wipe:- 'Alejo ti o ba ju onile lọ, iboji ni nwọn nfi sin jade" Ẹ parapọ ki ẹ jẹki a fi ibo ti ọjọ rẹ kusi dẹdẹ yi le ẹgbẹ "BABA ALAJỌ PIN" lugbẹ kuro lori ilẹ Oduduwa.

Lati Ọwọ Ẹrukobodo

## ẸLẸṢẸ YIO JIYA ẸṢẸ

Ọrọ Ọlọrun kan ti sọ wi pe Bi o ti wu ki enia mọ iwa to buru hu to, bi o pẹ titi ẹsan iwa buburu rẹ, o mbọ wa ke lori rẹ Nisisiyi ẹsan iwa buburu ti ẹgbẹ Dẹmọnu ti nhu si tom de tagba Ipin ẹ Iwọ Orun, nipa ki a so onile di ẹniti o nsun ita, onimoto di ẹnjti o nrinle, Ọga di ẹniti ko ri iṣẹ ṣe mọ, Alaiṣẹ di ero ẹwọn, olowo di onigbese ti o ti kari Ipinle Iwọ Orun Naijiria o to ki ẹ parapo fi ibo to mbo yi gbe de opin.

Asiko to fun ọmọ Yoruba to mbẹ ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati gboju so ke wo gẹgebi Ijoba ẹgbẹ Afẹnifẹre (A G) ti dara fun tọmọde tagba to. Lasiko Ijọba ẹ g b ẹ Afẹnifẹre ni Onile – koriko di ẹniti O nri owo fi kọle Panu; Alakisa di alaṣọ; Ope enia di Ọmọwe debiti Ọmọ akuṣẹ ndi Lọya Dokita ati akọwe agba lẹnu iṣẹ ninu Ipinlẹ Iwọ Orun kana yi.

Otitọ ni owe awọn baba wa sọ wipe:— Bi Obinrin ko ba ti de ile ọkọ meji, koni mọ eyi to dara ju ọkọn lọ. Ni alaiko tilẹ bere nkankan lọwọ ara wa, emi mọ wipe, iwọ ọrẹ mi to nka ọrọ yi, O ti rii daju gbangba wipe, Ijoba ẹgbẹ "AKẸ ỌNA KAKANFO" okoro ju Ewuro lo f u n tonile talejo ipinlẹ I w o Orun Naijiria.

## ILẸ DI AṢALẸ

Yoruba n i.- "Bokanran ko san fun Inaj", pipa lori tun ọpa. Bokanran ko san fun awọn Onisowo lasiko Ijoba ẹgbẹ Dọmọnu, gbogbo awọn Oyinbo Onisowo lo sa fi ilu silẹ; Awọn agbẹ Onikoko ti mbẹ ni u YỌTỌMI lasiko I j o b a ẹgbẹ Afẹnifẹre ti pada di ẹniti ko tun ri owo fi jeun mọ; Ilẹ oko ti a fi ngbin nkan si, ti o ti nso eso rere fun wa ti pada di Ilẹ Aṣalẹ. Iwọ ọrẹ mi eyi ko to ohun ti a le ro ni arojinlẹ a t i eyiti a le fi Ibo wa le Ijoba ẹgbẹ Dọmọnu lugbẹ patapata?

Moro wipe yio to meji tabi mẹta ninu ọmọ iwọ ọrẹ mi to nkawe yi ti nwọn ti ilọ si ile-ẹkọ ọfẹ ti Ijọ ba ẹgbẹ Afẹnifẹre da silẹ, nje awọn ọmọ na ti pari ẹkọ wọn ki ẹgbẹ JAGUNLABI O to le awọn oluko lugbẹ? tabi iyi tabi ẹgbọn rẹ obinrin ti ko iṣẹ meji to nṣe to ju kia pate-oja lasin oja, ti ko jẹki nwọn lẹ 'ỌWỌ-OSI" wọn mọ Bu ka to ti nta ọja ti nwọn ti fi ẹta inu le sọnọ, kọ ni eyi koni to ironu tun o debiti ẹo tun lọ dibo rẹ fun ẹgbẹ Dọmọnu?

Yoruba ni: "Boku fẹ, bi ko fẹ ṣe e nri oju Ọmọ—Oloku lode". Ẹgbẹ Akintọ la tan awọn agbẹ jẹ titi ko to, o tun ko iwọnba owo ti Iba fi san gbese fun wọn lo fi ran Ọgbọn enia lọ wo ọrọ Koko ni ilu Oyinbo Kini ẹ lero pe awọn ti nwọn fi owo gobọi na ron ọ le mu wa lẹhin oro ti Ọgbẹni Awosika mu lo? Ṣugbọn, BaBA ADINI" Oiri owo ran Ọgbọn enia lọ si ilu okere ṣugbọn ko iti ri owo osu m ta san fun awọn Oṣiṣẹ Nje eyi ko ti to ohunti ọmo Yoruba le ro larojinlẹ fi ibo wọn te ẹgbẹ Ọlọwọ lugbẹ yan yan?

## AWỌN ỌBA NKỌ

Yoruba ni "Igba ko le digba Oyinbo, ki a foju Egbo tẹlẹ" Bi Hausa ti di ẹniti o laju to tarin ilẹ Naijiria eyiti nwọn ti di ẹn ti o le sọ ede Oyinbo tan lo ke Ọya lọhun, ti nwọn tun di ẹniti o tun nsọ ede Oyinbo L'Eko nwọn ko ti fi ọlaju wọn huwa ẹriẹn kan si Ọba wọn debiti nwọn yio sọ owo Ọba wọn di KỌBỌ.

Bi Hausa ti nbu iyi fun Ọba wọn to, Beta lisan ni Ọgbẹni Ọlawọyin wọ de Afin Ọba Ilọrin ki o to de ro ẹ ọn, ṣugbọn, bi ẹgbẹ Dọmọnu ko ko ti bikita fun Ọba ilẹ Yoruba to, bi ọla ati iyi Ọba Alaiyelu a Adesọji Aderẹmi "ONILẸ ti a ge kuru si "ONI" ti iṣe olori ati baba fun gbo gbo Ọba ilẹ Yoruba ti po to, ẹgbẹ Dọmọnu fi abuku

kan an depo ti ko ba si wi pe, Baba oni baba tete te riba fun wọn ni, nwọn ti pinnu lati gbe AROLE-ODUDUWA" lo fun yan mu yanmu je leti ken ilu Agbadarigi.

Mo tun ke pe gbogbo ẹnyin ọmọ Yoruba ati pe, mo tun nfi han yin wipe, bi iwa ti ẹgbẹ Akintola nhu lori I j ọ b a wọn ba iẹ o h u n



Alagba ẸRUKOBODO

Iwa awa ọmọ Yoruba ka si ohun abuku fun Orilẹ ede Yoruba, o tọ ki a parapọ fi Ibo ti ọjọ rẹ kusi dẹde yi le ẹgbẹ Alabuku kuro nilẹ Oduduwa.

## ỌNA OPOSU

Pataki ti mo fẹ fi ye gbo gbo ẹnyin ọmọ Yoruba to mbẹ ni Ipinlẹ Iwọ O r u n Naijiria lori Kosi Alatako ti o pe ni ỌNA ỌPOSU to njade ninu I b o ti a

nmura lati di pe ki iṣe ohun ti o le ba yin lẹru, tabi ohun ti o le ẹmu nare ọkan ba yin rara F u n ohun ti o nṣẹlẹ ati eyiti o tun nṣẹlẹ ninu iwa ẹ g b ẹ Dọmọnu ti tomode tagba wa nri yi, ki wọn kuro ni kosi alatako mọ dogun ti a ngbọ yi, ki o pada di Kosi ALATAKO Ọna Ọgbọn, bi o ku irawọ k a n loju Ọrun ẹgbẹ UPGA ti wọle. Nitori pe, awọn ẹ ba KOSI ALATAKO t a b i, Ọ n a ỌPOSU ti nagọ ba ni nkan ni yio jẹ tiwọn ninu Ito na lagbara Ọlọrun ati lagbara Oduduwa to ni ilẹ rẹ.

## IBO EKO NKỌ ?

Lati ọjọ ti nwọn ti da ilu Eko ni awọn to daa silẹ ti mọ ni 'Eko akete I l e Ọ g b o n a t i pe lati igbana ni ẹnik ni ti ma pe ẹniti o ba wọlu ilu Eko ti ko ba gbọn ki Oluwarẹ o to ẹbọn iyoku di Ọrun alakeji re ma bọ.

Bi a ba ni ki a ma sọrọ Ibo ti ilu Eko emi ripe ko tun si ohun ẹọ mọ na, nitoripe lati ip lẹẹ ilu Eko ni tọmọd. tagba to mbẹ ni nu rẹ ti lọg ọi lori ju ile kilẹ lọ ninu ilẹ Naijiria, Ti mọ-'ara ilu Eko ri nwọn ti mọ Olooto oṣelu yato si jẹun jẹun oṣelu, Nwọn mọ Oniro yatọ oloto beni wọn ti mọ Alagabagede yato si Onijibiti,

Ni ọjọ ti ẹṣẹ ẹgbẹ Dọmọnu ti wọ u Eko ni wọn ti mọ wọn pei kori enikẹni to dino fun wọn wọle ati pe, lati ọjọ na ni nwọn to wa kan pe, Bigipongimogi ẹyọ kan ninu wọn kole di bo l'eko ko wọlu.

## ỌGA AGBA NKỌ?

Bi Eko ti lọ ẹgbẹ Akintola to, bi oti wu ki oni na ti ni ọla ati iyi to ọjọ ti nwọn ba ti daruko re po mọ Dẹmọ, I ti ọjọ na ni Oluwarẹ ti di ẹni ẹtẹ ati, ẹni abuku larin ilu Eko.

Ọga mi kan oke ọhun bi Ọla ti Okiki rẹ, ti kan ilu to, ni ọjọ ti o di ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ nu l'eko ni ọla ati iyi re ti

Wo Oju Ewe Karun

# Iwe si Olotu Irohin Imolę

## Ęgba Ọmọ-Lisabi, O Di Ọwọ Nyin O

Olotu Inu mi yio dun pupọ bi ẹ ba le gba mi ni aye kekere yi lati ba awọn ọmọ ilu mi Ęgba sọrọ lori Ibo Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti ao di ni ọjọ kọkanla oṣu kẹwa ọdun yi.

Mo bẹ ẹnyin ọmọ Ęgba lati jọwọ ki ẹ jẹki a dibo fun awọn aṣoju ẹgbẹ Ajumọṣepọ (UPGA) ni ọjọ Idibo, ki a gbe Alhaji D S. Adegbenro ati Oloye Coker wọle, ki Alhaji Adegbenro le di Alakoṣo Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun.

Nitori ti Adegbenro bidi Alakoso Ipinlẹ Iwọ Orun iwuri nla ni yio jẹ fun awa omo Ęgba, anfani ati ire isẹ Aje yio si wo ilu Ęgba.

Nitori'na mo bẹ ẹnyin omo Ęgba lokunrin ati lobinrin papa julo ẹnyin Baba ati Iya wa lati ronu yin daada lori bi ifaṣẹhin ti wa fun awa Ęgba ati ilu Abẹokuta lati igbati ẹgbẹ Dẹmo ti wa lori akoso Ijọba Ipinlẹ ẹ dibo fun ẹgbẹ itẹsiwaju (UPGA).

Emi ni
J. Bajus
ABĘOKUTA

nu iwe rẹ akọmọlede lati kesi gbogbo ọmọ ilu Ila—Orangun lori ibo Ipinlẹ Iwọ Orun ti o mbọ yi

Ẹnyin Baba mi ati Iya mi, ẹ'ẹgbẹ lokunrin ati l'obirin ti o ba nfẹ Ijọba kire o kari ni Ipinlẹ Iwo Orun ti o si tun nfe ijade olori awa ọmọ Oduduwa ti o wa logba ẹwọn nisiyi ki ẹ jẹki a dibo fun Aṣoju ẹgbẹ Ọlọrẹ ogbeni E Aborishade ni ojo idibo na

Bi gbogbo wa ba le dibo fun ẹgbẹ Ọbuga wole, gbogbo nkan ti awa omo ilu Ila nfẹ ni ilu wa ni ẹgbẹ ite siwaju yi o ṣe fun wa

Ẹ maṣe dibo fun ẹgbẹ Dẹmo nitori lati bi odun mẹta ti ẹgbẹ Dẹmo ti nṣe Ijọba Ipinlẹ na ko si ore ti nwon ṣe fun wa ni Ilu Ila, nitori na ẹ jẹki a ko ẹgbẹ Dẹmo ki a si fi tokantokan dibo fun egbe Ọlọpẹ ati ati Alakuko

Emi ni
Samuel Ladipo
ILA—ỌRANGUN

## A Nfẹ Iwasu Ninu Irohin-Imolę

Olotu dakun gba mi ni aye ranpe inu iwe yin olo yin mọmọ ti nkọ wa lede Yoruba lati kesi awọn oni Gbagbọ ododo lati mase Iwasu sinu Iwe Iroin Imọle mo tun kesi awọn Onimalo ati ma wasu peju.

Ben ni mo tun kesi Woli S L Kegberegbe Ọgbeni S O Jaiye Ọgbeni Bamidele ti ilu Esie ati Alhaji Y A Disu asi nfe ọrọ iwasu lati enu awọn ojigbo ti mo da rukọ re yi

Ọlorun k ni jeki o re nyin amin sugbon ohun ti yio dara ju nipe ki Imole ba nse iwasu tirẹ akofe ko mase eke eebu si onigbagbọ atipe to ba se awon na se eke eebu na pelu

Eleyi yio dun mo awa ti nka Irohin-Imole ti nwon ba se eleyi fun awon onka we Iroh n Imọ e olotu mo dupefun aye ti egba mi oko ọpọ koni sa nyin teeco

Emi ni
ỌNAADEPO EJỌRUN
EṢIẸ

## Obinrin Di Golu Ni Ipokia

Olotu:— Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi l ye ranpẹ ninu iwe nyin Olovinmọmọ ati so oro gbolohun mẹta tabi merin lati kesi Ijoba Ibilẹ ti Ipokia lori oro Wundia ti owo kekere ko kun awon obi l ju eleyi yio san fun gbogbo odomokunrin ilu Ipokia bi awon Ijoba Ibilẹ Ipokia ba le ṣe ofin kan ti yio ṣe pato lori owo ori olomoge

Nwon ni bi oju ba la ni alaju oko olowo ni ipẹkun rẹ. Oju asalama si ti awon wundia Ipokia a ni ofẹ ba gbogbo nkan jẹ mo won loju.

Inu wa yio dun bi Ijoba ibilẹ Ipokia ba ṣe iranlowo fun wa lori nkan ti awon Wundia ilu na ndanwo yio si dara pupo ju.

Mo dupẹ pupo o Olotu fun aye ti ẹ gba mi Ọlorun ko ni jẹki nkan abuku, oko oba ko ni ṣa nyin lẹsẹ e.

Emi ni,
Yisa Yusufu,
IPOKIA.

## Aborishade Ni Awa Nfẹ

Dakun Olotu mase alaiko gba mi ni aye kekere yi ni


## Bọ Lọwọ Ọṣọ Ati Ajẹ

Iwe egbogi Ajẹbidan 25/- meji £2
Iwe Ilana Ifa Iyanrin titẹ ati etutu rẹ pẹlu Iwosan 20/- mejila £2
Iwe Egbogi Awogba Arun meji 40/-
Turari isẹgun Ajẹ Oṣo ati awọn abanijẹ O wa fun itaja pẹlu alakala Pangolo 10/6 Pakẹti 2/- Ki iṣe ti ẹnu fifọn bi o ra ninu awọn ọja yi aabo ti o ni ipon yio wa lori rẹ ati awọn ẹbi rẹ.

Fi owo ranṣẹ si

J O SHOYINKA
5 Alaba Street,
Odu abọrẹ Mushin

## Kere o ! Kere o !! Akiyesi Pataki




Awa na le jẹri wipe ojulowo hauhau egbogi gidi ni LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast Ankara Ghana pẹlu meji rẹ ko si ninu orisirisi Egbogi kakiri ilu Naijiria.

Bẹ na ni ẹwẹ ni Igboro ilu Eko Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde tagba ni asiko yi ti nwọn fi se oro ati orin latin ara won ni nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwon npe ni LEOPILLS.

Imoran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nse iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to ati o jẹ ojulowo giriki ati ara matase fun "JĘDIJĘDI" bi o ti wo ki ojo re ti pẹ to bẹna ni nwọn ti tun fi owọ sọya tabi ṣe ileri fun gbogbo awọn ti amodi tabi iju, tabi Igbẹ siso, tabi aiko ri igbonsẹ deede. Inurirun nigbakugba ara wiwo. Esari, ẹhin didun sisan, abi aiko riran kedere ko doro buruku lara, aisan Onigba meji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu.

"Wipe nwọn yio ri alafia ni kiakia ti nwọn ba nlo egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹjẹ ṣe lara enia nipa sisọ di ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ỌRỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS.- Igo nla sile meje abọ (7/6) pere Igo kekere sile merin (4/) pere. Bere Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi Amodi ti ẹ nba fe ni Ṣọbu awọn:-

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street Lagos
Phone 22878 (Oja Ita Faji)

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square Lagos

ATI NI ṢOBU

IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA IBADAN.

# AWỌN IWA IBAJE TO WA NINU ILE AIYE

Emi Ẹfufu Lẹlẹ de kere bi oyun mo si de rere bi aṣẹ. Loni bi mo tl mbọ si inu aiye la- ti wa bere iwa awọn ọmọ enia iha Iwọ Orun wo. Bi mo ti lọ juba Olodumare ti mo tuba niwaju Baba Nla ẹni Igbani. Bi o ti yẹ ẹnu Rẹ lati ran mi ni iṣẹ si awọn enia ile yi. na o.

Emi ni Efufu Lẹlẹ.
Ilu Orun nlọ o. iyoko tun di Ola O.

Ẹmi en Re mu ki mana mana ko iara beni ara san wa! wa!! wa!!! Ile mi titi igbi okun ru soke awọn eja ;nu rẹ damu gbogbo awọn runmọlẹ oku wa riri! fun :d mu.

Bẹni awọn ẹyẹ oju ọrun pa iyẹ wọn mọra, awọn hẹlẹhẹlẹ Awọn enia inu aiye fere ma tọ si ara nigba ti ara nsan wa; wọn fẹrẹ daku

## Lati Ọwọ

Emi Ẹfufu Lẹlẹ nwo awọn ẹlomiran ti o bori wọn mọlẹ i ri akete wọn. Nigbati mo wo wọn bi nwọn ti njiya ẹrin sọ ẹnu mi muṣẹ Bi awọn enia wọn yi ba nberu fun akoko yi. baw ni wọn yio ti se nl ojo idajọ ojo eru jeje? Kungu ylo sọ ni ojo ibẹwo mi! Ohuu to d ju nl oju saju ko si ni ojo na

Fu! fu!! fu u!!! mo ti fo de Ogbomoṣho ilu Olotu Iwọ Orun ti mo ti nra ta ba lori ilu nla yi n o duro ni ike Elerin fun die; mo koja lọ si ọja Igbo, mo de Isata lehin na mo de Banki ati Ijeru lọ si Gabapọn. Lẹhin na mo duro n agbe gbe Ile Isẹgun awọn enia Ọlọrun ti nwọn ti lo gbogbo akoko won fun Ire ilu na Bi mo ti kuro nibẹ ni mo lọ bẹ Ile Ol tu Iwọ Orun wo

Bi mo ti wọ ile ni gbogbo Ile wa riri ti nwọn si parọrọ fun iberu nitori w,n mo pe iranṣẹ Ọga Ogo wọle wa. nitorina kẹkẹ na mọ gbogbo wọnlẹn i Nwọn si dabi ku fu ib ru

Ba I ni ma na pa iye ni si olotu pe, kini de ti gbogbo awọn enia fi soro be. Ko tile le bere pe bawo ni nwọn iti ma esoro on? Ida hun to fun mi rip be ko Iwọ Iranṣẹ Ọga Ọgo !!!

Mo bere lọwọ re pe kini de ti o fi jẹ ki awọn ọlọpa ibilẹ fi mu onisẹgun kan ati amofin kan lo hi mo ile? Bi o ti yẹ ẹnu rẹ, ete re nigbọn fun iberu.

Emi Efufu lẹlẹ ba ol tu yi sọrọ pe igbe ohun agonni ti de ọdọ mi fun ayewo. bi mo ti pe kuro bibi ni o tẹri ba pe Oluwa mi kin ndin akara die fun n ii t pe ọmọ agutan kekere kan wa nihin yi lati pa fun alejo nyin.

Bi mo ti w fun pe d i o emi k yio je ninu onje adidun re, loṣe kan na ni o wa dami lohun pe, se o mọ pe B ba w Abrahamu na ṣe iru alejo ti r o f se yi?

Ẹṣe i o ri lati ko onje te mi? mo wo, mo rẹrin fun ogbon ati ete rẹ, emi Efu fu lẹlẹ i l je bẹ emi ki imu omi, kini anfani onje rẹ ti awọn enia inu ile rẹ ko gba dun? kini o fa ki nṣe nisiyi?

## Ẹfufu Lẹlẹ

Nitori lati ọjọ ti ọrọ Idi bo ti wa aye ni mo tiri gbo ọ̀o ilana ti e fi le ile kinla! o ko ha mọ pe ododo ni ngba orilẹ ede leke? o to ge emi k ton fe ede ai ede ni Iwọ Orun ile yi mọ

Kini ṣe ti gbogbo awọn ọmọ ipinlẹ rẹ fẹran owo be t? ki i se ti Idarud pọ fi Ijọba ni okan omo I wo Orun bayi?

Dahun si ọrọ mi yi, Mo ti ri ẹna ti ẹ ti fi le lo pa awọn kan ke ri ave gbi iwe nwọn si awọn Olotu Idibo

Kini ṣe ti a ko fun gbo gbo enia laye lati ṣe eto idi bo nwọn ni aw n ọna to to? Ile ti a ba fi itọ mọ iri ni yio wo yanyan. Ojo o e ọfẹ nyin ti hi ile lati rona pi wida si ọna ododo.

Emi Ẹfufu Lẹlẹ ko ni inu didun si iparun ọmọ enia nitorina mo npe gbogbo ọmọ Iwọ Orun si atunse gbogbo nkan Emi Ẹfufu Lẹlẹ duro lori ọtọ aiye mo si n w o awọn nkan miran ti o mbọ wa sẹlẹ lori gbogbo awọn aiwabi Ọmọ Ọlọrun.

Emi Efufu Lẹlẹ n w o nyin ẹnyin ẹnyi, Ọmọ Ihi Ila Orun toto Odigbo diẹ

# Yoruba Ko Gba Gbẹrẹ

## Lati Oju Ewe Kẹrin

ṣe ma se nkanti igbakeji rẹ ẹ koni mọ ti yio wa je pe w n ọmọ ẹgbẹ lasan-lasan yio mọ pe irọ nla ni eyi Ọba oke yio dajọ.

Lati igbati rogbodiyan yi ti bẹrẹ ni isokan ati irẹpọ ti sa kuro n lẹ Yoruba patapa Ijọba Idera owo atl alafia si jinn si wa n tori na ogun karun ti o si run je awure gidi gidi fun awa Yorubi t yio si tun da gbogbo awon ohun alumọni olo o iyeb- ye ti o ti salo ni ẹ yi padi ni ibo yi itori di o wo awa enia Ipinlẹ Iwọ Orun ẹ ma ṣe jeki eleyi o bo lowo wa o ẹ jeki a mura gidig di latija gun Oduduwa aja ṣẹgun

Oluwa yio si ra wa lowo jẹki gbogbo wa fi ibo da Oloye Awolowo lare ẹ si ri anu Awolowo ẹniti o ni fe awa mẹkunnu laka ti o si tun ni ya eitori wa.

Enyin ẹ tilẹ wo na gbogbo ẹi nwon ti nfitina rẹ to yi ko binu rinu ewon ni o wa ni akobi omo rẹ de lati ilu Oyinbo ti o gba opolo poye ninu ofin i o si pa da agbako iku ninu jamba m to nitori di eyi mo bẹ ẹnyin adibo Ipinlẹ yi e dibo fun ẹgbẹ itẹsiwaju ẹ gbagbe D mọ danu ni Ipinle Iwọ Orun fi ibo rẹ da Oloye Awolowo lre.

## Lati Oju Ewe Keji

bọ sinu igbimi oku ẹga ti t'ọmọde t'agba ilu ti ora baba fun, o pada di ẹniti o tun nwotun wosi ki o to le rin larin ilu, eyti awọn agbalagba npa lowo wipe:- Abu u ala ju mọje'e lọ lara enia.

Nitorina, bi a ba ns ro Ibo didi kc t ki a ma fenu kan ibo didi fun ọmọ ẹgbẹ BABA ALAJOBI ni igboro Eko, nitoripe Ijẹkọjo ti ọro ibo didi ba wa saye, Eko ti pinnu lati diho won fun UPGA ti "YỌTỌMI".

Nipa ọrọ mi, ẹ fi ibo yin le Dẹmọnu lagbẹ ki atubọtan ọmọ Yoruba le dara.

A Tun Gbe De !

Iwe itan igbesi aiye Oduduwa ati ti awọn ọmọ rẹ Iwe yi kun fun itan isẹdalẹ. Kedere ni Aworan Oduduwa ati awọn ọmọ rẹ han ninu rẹ. Maṣe jeki nwon o robin rẹ fun ọ Sile meta 3/- pere ni a nta, Postage 9d,
Kọwe Fun Dọsinni rẹ:—

Tete fi owo tirẹ ranṣẹ si

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Idumagbo Avenue, Lagos Nigeria
(Leti Ọja Jankara) EKO

